# MIMO OFIN OMINIRA IWIFUN ODUN 2011

## KOKO MEWA PATAKI TI O JEYO NINU OFIN OMINIRA IWIFUN ODUN 2011

## ATI

## ITAN MEWA NIPA OFIN OMINIRA IWIFUN ODUN 2011

**Atejade lati owo**

R2K RIGHT TO KNOW ....YOUR LIFE DEPENDS ON IT

**Pelu Asowopo**

OPEN SOCIETY INITIATIVE FOR WEST AFRICA

ERONGBA

Lati se iranwo ilosiwaju ijoba ti wa ni tiwa, ti ko ni eja nbakan ninu nipase pipolongo ki iwifun wa ni arowoto gbogbo eniyan, kikopa nuni isejoba ati ibasepo pelu agbebe awon awako, awon eniyan ati ara ilu, awon egbe awujo ati awon ajo ti ijoba.

**KOKO MEWA PATAKI TI O JEYO NINU OFIN**

**OMINIRA IWIFUN**

**Lati owo**

**Ene Enonche**[i]

Ofin ominira iwifun ti orile ede Naijiria ti Aare Goodluck Jonathan fi owo si ni ojo kejidinlogbon osu karun egbewa odun le mokanla ni o le mu ayipada rere ba isejoba adowobo ti o ti wowa lewu ni orile ede yi titi di oni. Oye ti ofin yii n fihan ni wipe awon osise oba ni olupamo asiri, eyi ti won nse loruko gbogbo ara ilu, ti gbogbo ara ilu si leto ati mo ohun ti awon osise oba naa nse. Ofin yi seleri lati samukuro bi osise oba se so ise oba di ohun iyanu ti a ko le mo idi re. Apinleko yi safihan koko mewa ti ofin naa pese.

1. **Ofin Ominira Iwifun ju ofin asepamo ijoba**
   Ilana kini ninu ese keji ofin yi fun enikeni ni eto lati beere fun iwifun, boya iwe-iran tabi afenuwi, ti o ba wa ni ipamo ni sakaani osise oba tabi ile ise oba. Eto yi je eyi ti ofinkofin yowu ki o ti wa tele ko le se adinku tabi idena fun. Eyi ti o ja si wipe ofin ominira iwifun lagbara ju ofin asepamo ijoba, sugbon ofin yi ko ni iru ipa bee lori ofin ile ise abo orile ede, nitori wipe ofin abo yi ni o wa ninu ofin apapo ile wa eyi ti o si ti ni alakale ona ti a fi le se atunse re ninu ilana keji, ese kesan ofin apapo ile wa.

2. **Enikeni ni o le beere fun Iwifun labe ofin yi**.
   Eto labe ofin yi ni o wa fun lilo enikeni, laifi ti ojo ori, eya tabi ede se, lati ni larowoto iwe-iranti ijoba ti o ba wa ni ipamo ile ise ijoba tabi ti aladani ti o ni ojuse tabi ise fun ara ilu. Ofin yi fi aye sile fun alaabo ara tabi eni ti ko kowe lati je ki elomiran ba oun ko iwe ibeere fun iwifun. Ofin yi fayesile wipe ko pon dandan ki oro tabi iwe-iranti ti eniyan nbere iwifun le lori o je eyi ti o kan eni ti o nbere gbongbon.

3. **Idahun si Ibere Iwifun ni o gbodo jade laarin ojo meje.**
   Ese ikerin ati ikarun ofin yi so wipe ile ise ijoba gbudo fi iwifun ti a bere si arowoto eni ti o nbere re laarin ojo meje. Ti idahun si ibeere ko ba si ni ile ise ti a kowe ibeere si ti o si je wipe ile ise miran ni o wa, ile ise ti a kowe si ni ofin fun ni ojo meta lati dari iru ibere bee si ile ise ti o leto ati dahun.
   Ti idahun si ibeere iwifun kan ba je ohun ti o po pupo, ofin fi aye sile fun afikun ojo meje miran, yoo wa je ojo merinla. Fun idi kan tabi omiran labe ofin yi ti ile ise kan ko fi ni fi iwifunni ti a beere si arowoto eni ti o beere, ile ise bee yoo kowe si eni ti o beere lati salaye idi ti ko fi le ri iwifun ti o nbeere fun gba.

4. **Ese kewa ofin yi ko fayegba biba akosile je tabi yiyi akosile.**
   Ese yi je ese si orile ede labe ofin yi, eyi ti o le fa ijiya ewon odun kan o kere tan fun osise ti o ba da ese yi tabi oga ile ise ti o ba da iru ese yi. Ilana karun, ese keje pase owo itanran idaji milionu kan naira (₦500,000.00) ti enikeni tabi ile ise ti ile ejo ba da lebi wipe o gba ona aito lati ma je ki iwifun wa ni arowoto eri ti o bere fun lori akosile ijoba.

5. **A le gba owo fun sise eda akosile.**
   Nitooto ni iwifun wiwa ni arowoto ara ilu je ofe, sugbon ese kejo ofin yi fayegba ki a gba owo lowo eni ti a ba ma seda iwe-iranti fun. Sugbon oye owo naa ko gbodo ju oye ti a nse iru eda bee lawujo.

6. **Ile ise Ijoba gbudo ni Akosile ti o peye**.
   Ofin yi gbe ojuse apamo iwe-iranti ati iwifun nipa gbogbo ojuse ile ise le owo ile ise ijoba. Ofin yi ni o tun so di dandan ki ile ise ijoba o da osise won leko lori agbekale ofin yi ati imulo re.

7. **Abo wa fun awon atanilolobo.**
   Ese Ketadinlogbon ofin yi seto abo fun osise ijoba lati ri wipe a ko le pe iru osise bee lejo tabi je niya titori wipe o tu asiri isipo lo, iwa ibaje, isowo ilu basubasu.

8. **Awon Iwifun kan wa ti ofin fi aye gba fun iyasoto.**
   Ese kokanla titi de iketadinlogun ofin yi ya awon iwifun ati iwe-iranti kan soto bi eyi ti a ko le mu wa si arowoto gbogbo eniyan.

9. **Eto wa fun riri atunse arowoto titi kan agbeyewo ile ejo.**
   Ofin yi fi aye fun gbogbo eniyan lati gbe ile ise ijoba yowu lo sile ejo lati kan nipa ki o tele ofin yi. Ofin yi tun fayesile ki eni ti a ba fi arowoto iwifun dun o pejo laarin ogbonjo. Ajo ile wa ti o nri si eto omo eniyan naa ni ipa lati ko labe ofin fun ririidoju wipe won samulo ofin yi ni ona to to.

10. **Adajo Ile Ejo Agbaye ni yoo je Alamojuto ofin Ominira si iwifun.**
    Ofin yi fi idi re mule pe offisi Adajo Agba ile Idajo ni yoo je alamojuto, olumuse ati oludari ofin yii. Lati ojo kinni osu keji odun kookan gbogbo ile-ise ijoba yoo maa fi akoole won sowo si Ile ise Adajo Agba yii iye ibeere fun iwifun ti won ko ati idi ti won fi koo. Iye igbejo ti won ti se lori ise bee, iye idalare ti ile ejo ti se nipa kiko ibeere fun iwifun. Iye owo ti won ti san lati se ise naa ati iye awon osise ti won lo.

**ITAN MEWA NIPA OFIN OMINIRA IWIFUNNI**

**Lati owo**

**CHIDI ANSELM ODINKALU**[ii]

Aare Goodluck Jonathan fi owo si ofin ominira iwifun ni ojo kejidinlogbon osu karun egbewa odun le mokanla. Pelu igbese yii, ofin yi di amulo. Itan ati isele atehinwa, awon eroja, ilana isofin ati amuse ijoba ti ofin yi wa fun ati oniruru isele ti o yi ofin yi ka ni o le dani ni okan ru. A gbiyanju lati fi enu kan die nibe.

**ITAN KINI: OFIN OMINIRA IWIFUN JE OFIN IROHIN**

**OTITO:** A se agbekale ofin yi lati ri wipe ijoba wa ni arowoto gbogbo eniyan bakanaa ati ki awon eniyan le kopa bakanaa ninu isejoba ohun Pataki ti ofin yi da le lori ni wipe gbogbo eniyan ti o ba nife ati mo bi a se nse ijoba le se be lai se laalaa. Awon eto inu ofin yi ni o wulo fun eni kookan ati akojopo eniyan. Pelu iwifun inu ofin yi, awon eniyan le gbe igbese ti o ye lati sise pelu ijoba, se ipinnu pelu oye ati seto lati je ki ijoba ati osise oba fun alaye lori isejoba. A lero wipe ofin yi yoo se iranlowo ati sadinku fun iroyin ati iwadii, fun aheso ti ko lese nle ati sisalekun iwadi ooto eyi ti o je ara a[iii]kosile ijoba. Aseyori eyi ko le seese ayafi ti awon osise oba ti o ni ojuse lati se imuse ofin yi ba se bee pelu okan otito. Ile ise ati awon onisowo yoo le samulo ofin yi naa.

**ITAN KEJI: AWON ASOFIN TI TOWOBO TABI SE ABULA OFIN OMINIRA IWIFUN YI KI O TO DI FIFOWO SI.**

**OTITO:** Ile asofin apapo kekere ni o fowo si ofin yi ni ojo kerinlelogun osu keji egbewa odun le mokanla ti Ile asofin apapo agba si fi owo si ni ojo kerindinlogun osu keta odun naa. Iyato mejila ti o se Pataki ni o wa laarin eya ofin yi ti ile asofin kekere fowosi ati eyi ti ile asofin agba fowosi. Iyato wonyi ni o safihan ohun ti o je iyato ti laarin oye ati ogbon isise ile asofin mejeeji. Nigbati ile asofin agba ri arowoto iwifun gegebi anfani, ile asofin kekere ri gegebi eto omo eniyan. Gegebi alakale eto isofin, ikokan ninu ile asofin nejeeji ni o gbe igbimo eleni mefa dide lati sakojopo erongba ile asofi mejeeji lori ofin yi. Igbimo won pari ise won ni ojo kokandinlogun osu karun ti won si safenuko lori mimo arowoto iwifun gegebi eto omo eniyan. Akojopo yi ni ile asofin mejeeji fi owo si ni ojo kerinlelogun osu karun. Akojopo yi ni o je ki ofin yi tubo munadoko si ju erongba akoko ile asofin kookan lori ofin naa.

**ITAN KETA: OFIN YI JE OFIN TI ASOFIN ABIKE DARIRI**

**OTITO:** Ofin yi je eso ifowosowopo laarin gbogbo omo orile ede yi, awon ajo oselu ati ijoba. Ofin yi waye lehin odun metadinlogun ti won ti gbe abadofin re kale, Ogbeni Edetaen Ojo ti oje oludari agba fun ajo ajaafeto lori irohin ni o koko sini niye lori ofin yi pelu atilehin ajo akorohin ti orile ede yi (NUJ) ati ajo ominira awujo (CLO). Akosile akoko ofin yi ni agbe kale ni e odun (1994) lati owo amofin agba Tunde Fagbohunlu pelu atilehin Oloogbe Bankole Aluko (agbejoro agba), Ogbeni Chidi Anselm Odinkalu. Asofin Abike Dabiri Erewa je ikan lara awon ti o satilehin ti o nipon fun ofin yi ni ile asofin apapo kekere karun, pelu iranlowo Ogbeni Ita Enang ati Dino Melaye. Asofin Dabiri ni ko iti di asofin ni osu kefa okandinlegbewa odun (1999). Awon ti o sagbateru ofin yi ni igba ti o koko wa si ile asofin ni Oloogbe Tony Anyanwu, Nduka Irabor, Jerry Ugokwe. Awon asofin wonyi ni o satilehin iwa fun ofin yi ni ile asofin lakoko, Ogbeni Victor Lar ti o je asofin agba, Ogbeni Nze Chidi Duru, Lad Ojomo ati Uche

Maduako ti gbogbo won je omo ile asofin ti ipele kerin. Lara awon alatilehin ofin yi ni ipade karun ati ikefa ile asofin apapo ni : Henry Seniake Dickson, Ojogbon Sola Adeyeye, Uche Onyeagucha, Haruna Yerima, Dokita Usman Bugaje, Ita Enang, Aminu Masari, Austin Apova eyi ti ile asofin apapo agba. Awon wonyi satilehin fun ofin yi: Ogbeni Wada ati amofin Victor-Ndoma-Egba. A ko sile fowo ro ipa ti asofin awon wonyi ko sonu kan: Nnamani, amofin Uche Chukwumerije, Inatimi Spiff, Ayogu Eze ati Julius Ucha.

**ITAN KERIN: OFIN LATI NI OMINIRA SI IWIFUN JE IDERUBA AABO ORILE EDE**

**OTITO:** Aabo orile ede Naijiria je ojuse gbogbo awon ti o n gbe inu re tabi ti o ti ibe wa. A ko le so pe ofin lati ni ominira si iwifun ko ka aabo orile ede si nitori on gbe orile ede laruge nipa fifi isokan han ati nipa didaabo bo ipolongo bi o se wa ni ori ketadinlogbon. Ofin lati ni ominira si iwifun se ipese fun imukuro awon nnkan kan ni ori ikokanla, ikokandinlogun ati ikerindinlogbon. Iwifun ti o se imukuro re ninu ofin yii wa ni isori ikokanla atunpinsisori kinni. "gbogbo iwifun ti o ba le se ijamba fun ise okeere ati aaabo orile-ede Naijiria" ati eyi ti a ko si isori kejila ipinsisori kinni, iwifun ti o le da iwadi iwa odaran ati ti agbofinro ni pataki awon agbofinro (Olopaa). Ofin yii fi agbara kun ofin eto alaabo ilu ti odun 1986 ti a tun fi idi re mule ni isori oodunrun o le marundogun ipinsisori karun-un (d) ti iwe ofin ile wa odun 1999 ti a si le se atunse re nipa akanse pataki ti o wa ni isori kesan-an ipinsisori keji iwe ofin ohun. Ofin eka aabo ara ilu se idasile eka meta pelu ojuse pataki fun idaabo bo aabo orile ede Naijira. Awon ni:

(a) Eka ti n fi oye se aabo fun idaabo bo oro to jo mo ologun (Soja);

(b) Eka ti n fi oye se aabo ilu- fun idaabo orile ede Naijiria leyin odi.

(d) Eka osise alaabo ipinle-fun aabo omo Naijiria laarin awujo.

A da olubadamoran nipa aabo orile-ede sile ninu isori karun ofin yii gege bi “alakoso aabo orile-ede” ori keji ipinsisori keta (a) ti ofin eka alaabo orile-ede ti o so pe ki osise alaabo ipinle maa “daabo bo gbogbo nnkan ti kii se ti ologun ti o ro mo aabo orile-ede Naijiria”. Eyi ni pe igbekale ofin eka aabo orile-ede yoo maa toka si awon iwe pataki paapaa awon iwe tabi iwe-iranti ti o le ni ifura si aabo orile-ede.

**ITAN KARUN-UN: A NILO OFIN OHUN IKOKO ABE ASE**

**OTITO**: A gba ofin ohun ikoko abe ase wole ni igba akoko ni orile ede Naijiria nipa ijoba Geesi ni odun 1911, a si se ifihan re si orile-ede Naijiria gege bi ilana amunisin pelu idapo. Ijoba Geesi ko ni ara ilu, omo eyin nikan ni o ni. Bakan-naa labe ijoba amunisin, ko si ara-ilu. Nigba ti ijoba amunisin dopin, awon ologun ni o se ijoba lopolopo igba eyi ti ko je ki asa bi a ti n jiyin/royin fun ara ilu fesemule. Ni abe oselu alagbada ni a ti ri eto si ofin, eto si idibo. Ofin ominira fun iwifun ni ona kan soso ti o fihan pe awon ara ilu ni eto lati mo ohun ti awon ti won fi ibo yan nse. Eyi ni wipe won ni anfaani lati ni iwifun. boya ki won maa se bi won se n see tabi kiwon se atunse tabi ki won mu ilana miiran lo ni ile Geesi nibi ti ofin bokele labe-ase ti jeyo, lore-koore ni won maa n se ayewo re tiwon si maa n tunse. Bayii, o wa ku sowo awon osise alaabo ati otelemuye. Nidakejii, gbogbo ofin bonkele abe-ofin ni akoko awon amunisin ni a ko gbeyewo tabi se atunse re ni ile Naijiria titi di akoko yii.

**ITAN KEFA: OFIN SI OMINIRA IWIFUN KO KAN AWON IPINLE**

**OTITO:** Ofin si ominira iwifun se amulo ofin meji pataki lara ojuse Ile Igbimo asofin. Ikinni, ni labe ege keta (d) ti ise keta (3rd Schedule) Ofin fun awon Ile Igbimo asofin ni agbara lati ni iwifun nipa dukia ti osise ijoba ni, Ikeji, Ipin ogota (a) ti ise keji (2nd Schedule) kun fun ilakale ojuse awon asofin ti o fun won lagbara lati sofin igbega ati ifagbarase erongba Pataki ati itosona ofin ti o ro mo ipinnu ipinle. Ni abala iwe ofin yi isori kerinla itunpinsisori keji (a) ofin ile wa fi idi re mule pe agbara nla wa fun omo Naijiria ninu eyi ti ijoba ti ri agbara ati ase, nigba ti isori kerinla ipinsisori (2) (d) so wipe”aaye yoo wa fun awon eniyan lati maa kopa ninu isejoba”. Ofin si ominira iwifunse amuse ojuse awon igbimo asofin. Lafikun, ipin (d) ti abala keji ti ise keji ofin so wipe awon asofin lee sofin fun isokan nipa ibi ti ijoba n fi iwe ilu tabi iwe-iranti pamo si. A ko se alai je ki ipinle se ofin nipa iwe-iranti, sugbon iru ofin bee yoo teriba fun ofin ti ijoba apapo ba se ti o bar rii pe ko se deede, ti o si lee pa ofin ijoba apapo lara. Nibi ti ipinle ko ba ti se iru ofin bee, ofin ominira fun iwifun yii ni ipinle yoo maa lo.

**ITAN KEJE: OFIN OMINIRA FUN IWIFUN YOO FAYE GBA AINIPAMO ARA ENI**

**OTITO:** Isori kerinla ofin ominira si iwifun “Ile ise Ijoba gbodo ko ibeere fun iwifun ti o ba jo mo iwifun ara eni”. ki o si so lekun rere iru awon iwifun ti a le ka si ti ara eni. Ni ibamu pelu nnkan ti o n sele ni agbeyewo nipa ominira si iwifun iyasoto lee waye lori pe alaafia awujo tewon ju ti enikan lo. Ni afikun ofin naa gege bi o se wa ni isori kerindinlogun se idaabo bo awon agbejoro/onibara won, awon eleto ilera, awon alaisan, awon oniroyin

**ITAN KEJO: OFIN SI OMINIRA IWIFUN LEE SE OKUNFA SISE IROYIN LONA TI KO BOJUMU**

**OTITO:** Dipo ki o se okunfa sise iroyin lona ti ko bojumu, ofin si ominira iwifun ni a gbe kale lati rii wipe ko ri bee. Awon ijoba ti o koja fi aaye gba ki a maa se awifun awon ile ise ijoba kookan eyi ti o fa ki awon oniroyin maa se imele ati aheso. Ni ti ofin si ominira iwifun, awon oniroyin ati awon yooku ti o ba fe te iwifun jade ninu iwe-iranti yoo maa wa okodoro iru iwifun bee. Bi o ti wu ki o ri, won yoo je akosemose ti o lee se alaye ona ti o n gba ri iwifun re. O see se, fun apeere, ni igbejo ti o ro mo oro ara eni tabi oruko rere, ile ejo lee titori aise aikiyesi ti o ye se ipinnu ona abayo tabi idajo. Ni tite oro aye ara ilu jade, ofin ominira si iwifun yoo din owo ti a fi n wa iroyin ku yoo si je ki a ri iroyin ti o see foote lu.

**ITAN KESAN-AN: KO SI AJO TI O LEE SE AMUSE OFIN SI OMINIRA IWIFUN**

**OTITO:** Ofin si ominira iwifun wa fun ile-ise ijoba, ajo ijoba tabi ile ise aladani ti o n sise fun ara ilu, ti o n se ojuse ara-ilu tabi ti o n lo owo ara-ilu. Itumo awon ipin to keyin ni a ya soto nipa ise ati ilana wiwo ofin. Gbogbo ile-ise ijoba ti o wa labe ofin yii yoo maa se iroyin fun adajo agba patapata ti o ni agbara ati ipa lati se amojuto ati lati jihin fun ile igbimo asofin lodoodun bi a se n se amulo ati ise ofin naa. Ile ejo lee se atunyewo ofin yii. Laisi ariyanjiyan, Ajo ti o n ja fun eto omo eniyan lee je ipejo lati se imuse eto ti ofin yii n so nipa re.

**ITAN KEWAA: A KO SETAN FUN OFIN SI OMINIRA IWIFUN**

**OTITO:** Awon ara ilu ti o setan lati lee yan awon asoju lati soju won ni Abuja, Ipinle ati ijoba ibile, ye ki o lee setan lati mo nnkan ti awon asoju won n se ti won ba debe!

[i] Ms. Enonche alamajuto Right to Information Initiative (R2K)

[ii] **ODINKALU,** Ikan lara awon igbimo egbe agbejoro ni o sise pelu egbe gbangba ipinle awujo. (Open Society Foundation).